**15.** Ọ̀rọ kò ri bẹ, ti kò ba ṣiwọ, dajudaju A o fi àṣọṣo rẹ̀ wọ ọ.

كَلَّا لَئِن لَّمْ يَنتَهِ لَنَسْفَعًا بِالنَّاصِيَةِ ﴿١٥﴾

**16.** Aṣọṣo ori opurọ, ẹlẹṣẹ̀.

نَاصِيَةٍ كَاذِبَةٍ خَاطِئَةٍ ﴿١٦﴾

**17.** Ẹ jẹ ki o pe awọn alabaro rẹ̀.

فَلْيَدْعُ نَادِيَهُ ﴿١٧﴾

**18.** Awa yio pe awọn ọmọ̀ ogun (Wa) ti nwọn le koko.

سَنَدْعُ الزَّبَانِيَةَ ﴿١٨﴾

**19.** Bẹ̃kọ, ma tẹle tirẹ̀, fi orikanlẹ (fun Ọlọhun) ki o si sunmọ Ọ.

كَلَّا لَا تُطِعْهُ وَاسْجُدْ وَاقْتَرِب ۩ ﴿١٩﴾

## *(97) Suratul - Kọdri*

سُورَةُ الْقَدْرِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Dajudaju Awa la sọ ọ (Al-Kurani) kalẹ̀ ni Oru Abiyi.

إِنَّا أَنزَلْنَاهُ فِي لَيْلَةِ الْقَدْرِ ﴿١﴾

**2.** Kini ohun ti o le mu ọ mọ ohun ti Oru Abiyi nã jẹ?

وَمَا أَدْرَاكَ مَا لَيْلَةُ الْقَدْرِ ﴿٢﴾

**3.** Oru Abiyi nã, o ni õre ju ẹgbẹ̀run ọ̀ṣù lọ.

لَيْلَةُ الْقَدْرِ خَيْرٌ مِّنْ أَلْفِ شَهْرٍ ﴿٣﴾

**4.** Awọn Malaika ati Ẹmi nã (Jibreel tabi Malaika miran) nsọkalẹ̀ ninu rẹ̀ pẹlu iyọnda Oluwa wọn fun gbogbo ọ̀rọ̀ kọ̃kan.

تَنَزَّلُ الْمَلَائِكَةُ وَالرُّوحُ فِيهَا بِإِذْنِ رَبِّهِم مِّن كُلِّ أَمْرٍ ﴿٤﴾

**5.** Alãfià ni titi ilẹ̀ yio fi mọ.

سَلَامٌ هِيَ حَتَّىٰ مَطْلَعِ الْفَجْرِ ﴿٥﴾

## *(98) Suratul - Bayyinah*

سُورَةُ الْبَيِّنَةِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Awọn ti kò gbagbọ ninu onitirà ati awọn ọṣẹbọ, nwọn kò yẹ

لَمْ يَكُنِ الَّذِينَ كَفَرُوا مِنْ أَهْلِ الْكِتَابِ وَالْمُشْرِكِينَ

nwọn kò gbò (lori aigbagbọ) titi alàyẽ fi de wa ba wọn.

منفكين حتى تأتيهم البينة ١

**2.** Ojiṣẹ kan lati ọdọ Ọlọhun ti o nka awọn takada mimọ́ kan.

رسول من الله يتلوا صحفا مطهرة ٢

**3.** Awọn tirà ti o jẹ ojulowo wà ninu rẹ̀.

فيها كتب قيمة ٣

**4.** Atipe awọn ti a fun ni tirà kò pin kelekele lãrin ara wọn afi lẹhin ti alàye de wa ba wọn.

وما تفرق الذين أوتوا الكتب إلا من بعد
ما جاءتهم البينة ٤

**5.** A kò pa wọn laṣẹ ju pe ki nwọn jọsin fun Ọlọhun lọ, ki nwọn fọ ẹsin mọ̀ fun U, ki nwọn ṣe dẽde ki nwọn mã gbe irùn duro, ki nwọn mã yan saka atipe eyi ni ẹsin ti o duro dede.

وما أمروا إلا ليعبدوا الله مخلصين له الدين حنفاء
ويقيموا الصلوة ويؤتوا الزكوة وذلك دين
القيمة ٥

**6.** Dajudaju awọn alaigbagbọ ninu awọn ti a fun ni tirà ati awọn ọṣẹbọ yio wà ninu ina Jahannama, ninu rẹ̀ ni nwọn yio ṣe gbéré si. Awọn eleyi ni ẹ̀da ti o buru.

إن الذين كفروا من أهل الكتب والمشركين
في نار جهنم خلدين فيها أولئك
هم شر البرية ٦

**7.** Dajudaju awọn ti o gbagbọ ni ododo ti nwọn si nṣe rere, awọn eleyi ni ẹ̀da rere.

إن الذين ءامنوا وعملوا الصلحت أولئك
هم خير البرية ٧

**8.** Ẹsan wọn mbẹ fun wọn lọdọ Oluwa wọn: Ọgba idẹra ibugbe ti yio wà titi ti awọn odo nṣàn ni abẹ wọn,nwọn yio ṣe gbéré sinu rẹ̀ lailai. Inu Ọlọhun yio dùn si wọn, inu awọn na yio dùn si (ohun ti Ọlọhun ṣe fun wọn). Eyi wà fun awọn ti o bẹru Oluwa wọn.

جزاؤهم عند ربهم جنت عدن تجري من تحتها
الأنهر خلدين فيها أبدا رضي الله عنهم ورضوا عنه
ذلك لمن خشي ربه ٨